# Àkíyèsí Àìdẹ́yẹsíni

Àwọn agbaṣẹ́ṣe ìtọ́jú ìlera Johns Hopkins pẹ̀lú gbogbo àwọn òṣìṣẹ́ Johns Hopkins Medicine máa ntẹ̀lé àwọn òfin ẹ̀tọ́ ará ìlú ti Ìjọba Àpapọ̀ tí ó bá a wí wọn kìí síí dẹ́yẹsíni lòdì sí, ṣe àyọkúrò, tàbí hu ìwà ọ̀tọ̀ sí àwọn ènìyàn látàrí ẹ̀yà, àwọ̀, orírun, orílẹ̀-èdè tí wọ́n ti ṣẹ̀ wá, ọjọ́ orí, èdè, àìlera àfojúrí tàbí ti ọpọlọ, ẹ̀sìn, ìwòye akọ-n-bábo, pẹ̀lú ìdánimọ̀ tàbí ìyàn akọ-n-bábo. Lára àwọn àjọ tí ó ntẹ̀lé Àkíyèsí yìí (lápapọ̀ “Àwọn Àjọ John Hopkins Medicine”) ni gbogbo àwọn agbaṣẹ́ṣe ìtọ́jú ìlera John Hopkins tí ó npèsè ìtọ́jú ìlera fún ará ìlú ní àwọn ojúkò wọn àti àwọn òṣìṣẹ́ John Hopkins Medicine, títí kan gbogbo àwọn ojúkò tí a tòkọ sínú Àkíyèsí yìí.

Àwọn Àjọ Johns Hopkins Medicine:

- npèsè àwọn ìrànlọ́wọ́ àti iṣẹ́ ìtọ́jú ọ̀fẹ́ fún àwọn ènìyàn tí ó ní àìlera láti bá wa sọ̀rọ̀ ní ọ̀nà tí ó múná dóko, bí àwọn ògbifọ̀ èdè odi tí ó kọ́ṣẹ́ mọṣẹ́; ìfitónilétí tí a kọ sílẹ̀ ní àwọn ìlànà míràn (títẹ̀ ní ọ̀nà tí ó tóbi, ti ohùn, àwọn ìlànà orí ẹ̀rọ tí a ráàyè sí, àwọn ìlànà míràn); pẹ̀lú
- npèsè àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú èdè lọ́fẹ̀ẹ́ fún àwọn ènìyàn tí èdè wọn àkọ́kọ́ kìí ṣe èdè Gẹẹsì, bí àwọn ògbifọ̀ tí ó kọ́ṣẹ́ mọṣẹ́ pẹ̀lú ìfitónilétí tí a kọ ní àwọn èdè míràn

Tí o bá nílò àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú yìí, ìwọ tàbí aṣojú rẹ lè fi tó ọmọ ikọ̀ ìtọ́jú rẹ kan létí, bíi nọọsì, òṣìṣẹ́ iṣẹ́ gíga, tàbí oníṣègùn.

Tí ìwọ tàbí aṣojú rẹ bá gbàgbọ́ pé Àjọ Johns Hopkins tí o ti ngba àwọn iṣẹ́ ìtọ́jụ́ ìṣègùn ti kùnà láti pèsè àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú yíí tàbí wọ́n ti dẹ́yẹ sí ọ ní ọ̀nà míràn látàrí ẹ̀yà, àwọ̀, àìlera, tàbí ẹ̀yà akọ-n-bábo, ìwọ tàbí aṣojú rẹ lè kàn sí ọfiisì Ìbáṣepọ̀ Agbàwòsàn láti fi ẹ̀sùn tàbí ẹ̀hónú kan kalẹ̀. Tí o bá nílò ìrànlọ́wọ́ ní fífi ẹ̀hónú rẹ kalẹ̀, o lè gba ìrànlọ́wọ́ láti ọ̀dọ̀ Ọfiisì Ìbáṣepọ̀ Agbàwòsàn tàbí ibi kíkàn síni míràn tí ó yẹ ní Àjọ Johns Hopkins Medicine (JHM) rẹ. Wo wẹbsaitì àwọn Ẹ̀tọ́ àti Ojúṣe Agbàwòsàn JHM fún ìfitónilétí nípa kíkàn síni láti fi àwọn ẹ̀sụ̀n àti ẹ̀hónú rẹ kalẹ̀.

Ó tún lè ṣe àfikalẹ̀ ẹ̀sùn ẹ̀tọ́ ará ìlú ní Ẹ̀ka Ìlera àti àwọn Iṣẹ́ Ìtọ́jú Ọmọnìyàn ti Ilẹ̀ Amẹrikà, Ọfiisì fún àwọn Ẹ̀tọ́ Ará Ìlú nípa ìfiwéránṣẹ́ tàbí foonù ní:

U.S. Department of Health and<br>
Human Services 200 Independence<br>
Avenue, SW Room 509F, HHH<br>
Building Washington,<br>
D.C. 20201<br>
1-800-368-1019, 800-537-7697 (TDD)<br>
Àwọn fọọmù ẹ̀sùn wà ní àrọ́wọ́tó ní http://www.hhs.gov/ocr/office/file/index.html

Ọjọ́ 28, Oṣù Kejì, Ọdún 2022